## AWỌN ỌRỌ IYANJU FUN AWỌN ONIGBAGBỌ́

**1 Peteru 3:1-22; 4:1-19; 5:1-11**

**ẸKỌ 453 – FUN AGBA**

**AKỌSORI: "Ọlọrun ore-ọfẹ gbogbo, ti o ti pè nyin sinu ogo rẹ̀ ti kò nipẹkun ninu Kristi Jesu, nigbati ẹnyin ba ti jiya diẹ, On tikarãrẹ, yio si ṣe nyin li aṣepé, yio fi ẹsẹ nyin mulẹ, yio fun nyin li agbara, yio fi idi nyin kalẹ" (1 Peteru 5:10).**

**I Awọn Aṣẹ Peteru fun Ijọ**

1 Peteru sọ iṣẹ awọn ọkọ, o si ṣe alaye bi awọn obinrin Onigbagbọ́ ti ni lati wọ aṣọ, 1 Peteru 3:1-7; 1 Kọrinti 7:13-16; Efesu 5:22-25

2 O gba ni niyanju si ifẹ ati iṣọkan, ati lati jiya pẹlu igboya fun Kristi, 1 Peteru 3:8-18; 4:5, 7-11; Romu 12:10; Kolosse 3:12

3 Kristi waasu fun awọn ẹmi ninu tubu ki o to goke re Ọrun, 1 Peteru 3:19-22; 4:6

4 Awọn Onigbagbọ́ kò gbọdọ ka a si ohun ajeji nigba ti wọn ba bọ́ sinu idanwò gbigbona, 1 Peteru 4:12-19

5 Awọn alagba ni lati maa fi tifẹtifẹ bọ́ agbo Ọlọrun, 1 Peteru 5:1-4; Iṣe Awọn Apọsteli 20:28; 1 Timoteu 4:16

6 Ẹ jẹ onirẹlẹ, ẹ maa wà ni airekọja, ẹ maa ṣọra; eṣu ọta yin n wá ẹni ti yoo pajẹ kiri, 1 Peteru 5:5-10; Luku 22:31; 1 Tẹssalonika 5:6.

## ALAYE

### Ojuṣe awọn Aya ati awọn Ọkọ

Nipa aṣẹ Ọlọrun ni a fi ọkunrin ṣe olori ile. O le jẹ ẹni ti ko gba Ihinrere gbọ́, sibẹ oun ni ori a si gbọdọ huwa si i bẹẹ niwọn igba ti iwa rẹ̀ ko ba lodi si aṣẹ Ọlọrun. O ṣe e ṣe pe nipa iwa aya a le jere ọkọ naa fun Oluwa. Nipa ẹmi ọ̀wọ ati ifẹ aimọti-ara-ẹni-nikan ti o wà ninu Sara, oun a maa pe Abrahamu ni oluwa, ṣugbọn a ko gbagbọ pe Abrahamu huwa si i gẹgẹ bi ẹni pe ẹru tabi ọmọ-ọdọ ni.

Ifẹ ti o wà laaarin ọkọ ati aya gbọdọ jẹ ifẹ kikún lati ọdọ awọn mejeeji. Bi a ba jẹ Onigbagbọ a ni lati jẹ alajọpin ninu ohun gbogbo ti o jẹ mọ́ igbesi-ayé ọmọ eniyan: iṣẹ́, kikẹgbẹ pọ̀ ati ọran ifẹ. Ohun ti o wú obinrin lori ninu ọkunrin ni agbara ati igboya. Ohun ti n wu ọkunrin lara obinrin ni ẹwà ati ṣiṣe ifi-ọkàn-tán. Ẹwà ati iwà ṣe pataki lọpọlọpọ ju ẹwà oju ati ẹwà ara lọ. Obinrin jẹ ohun-elo alailagbara o si n fẹ lati gba iranlọwọ agbara ti ọkunrin le fi fun un; ifẹ ati iwa ifọkansin ti obinrin n fi hàn a maa wú ọkunrin lori.

Peteru ni wọn jẹ́ ajumọjogun oore-ọfẹ Ọlọrun. Bi wọn ba jẹ ajumọjogun nigba naa wọn jẹ́ ẹgbẹ́ kan naa ni ọna ti ẹmi. Wọn gbọdọ jẹ alajọpin ayọ̀ ati ibanujẹ wọn, aṣeyọri ati ijatilẹ wọn.

### Iwọṣọ Awọn Obinrin

Imọtoto ati iwọtunwọnsi a maa rin pọ̀ ni ifọwọsowọ. Ifẹ inu obinrin gẹgẹ bi ẹda ni pe o n fẹ ki ifarahàn oun ki o fanimọra. Ṣugbọn obinrin Onigbagbọ́ ko fẹ ọpọlọpọ ọṣọ aṣerege lati mú ki o lẹwa. Kò si bi tonitoni ti le pọ̀ to ki a fi dipo ẹmi irẹlẹ ati iwa tutu. Oluwa a maa wo ọkàn; bi ọkàn ba ṣe deedee iwọṣọ yoo wà ni titọ bẹẹ pẹlu. A sọ fun wa pe awọn obinrin Keferi igba ni n fi wura si ara irun wọn lati mú ki irun wọn tubọ lẹwa. Eyi n sọ itumọ "irun didi" ti Peteru n sọ. Owó rẹ̀ pọ; ko si bi aṣọ wiwọ ti le ni owó lori to ki a fi rọpo iwa eniyan ti o kún fun oore-ọfẹ. Ifẹ inu obinrin Onigbagbọ́ ni lati fi hàn nipa igbesi-aye rẹ̀ ati ifarahan rẹ̀ pe ọmọ-ẹyin Kristi ni oun iṣe; ki i ṣe lati polowo ara rẹ̀, ki o fa oju awọn eniyan si ọdọ ara rẹ̀ nipa wiwọṣọ ni ọna ti ko yẹ ọmọluwabi tabi lilo ohun ọṣọ ti o niyelori ju.

**Fun Awọn Ẹmi ninu Tubu**

Eyi jẹ́ ẹsẹ Ọrọ Iwe Mimọ́ ti o ṣoro lati mọ itumọ rẹ̀. Ọrọ Ọlọrun nikan ṣoṣo ni a le fi tumọ Ọrọ Ọlọrun. A mọ̀ pe ni akoko ti o wà laaarin ikú Jesu lori agbelebu ati ajinde Rẹ̀ O lọ si Paradise, nitori O sọ fun ole ni lori agbelebu pe “Loni ni iwọ o wà pẹlu mi ni Paradise.” Peteru n waasu fun awọn eniyan ni Ọjọ Pẹntekọsti, nipa ajinde Jesu o si lo Ọrọ ti ó wà ninu Ofin Dafidi 16:10; “Nitori iwọ ki yio fi ọkàn mi silẹ ni ipò-okú, bẽni iwọ ki yio jẹ ki Ẹni Mimọ́ rẹ ki o ri idibajẹ.”

Paulu sọ fun wa ninu Efesu 4:7-11 pe, “Ṣugbọn olukuluku wa li a fi ore-ọfẹ fun gẹgẹ bi oṣuwọn ẹ̀bun Kristi. Nitorina o wipe, Nigbati o gòke lọ si ibi giga, o di igbekun ni igbekun, o si fi ẹ̀bun fun enia. (Njẹ niti pe o goke lọ, kili o jẹ, bikoṣepe o kọ́ sọkalẹ pẹlu lọ si iha isalẹ ilẹ? Ẹniti o ti sọkalẹ, on kanna li o si ti goke rekọja gbogbo awọn ọrun, ki o le kún ohun gbogbo.) O si ti fi awọn kan funni bi apọsteli; ati awọn miran bi woli; ati awọn miran bi efangelisti; ati awọn miran bi oluṣọ-agutan ati olukọni.” A tun ri ifarahan ẹsẹ Iwe Mimọ́ yii kan naa lọna ti o wu ni ninu Orin Dafidi 68:17, 18, “Ainiye ni kẹkẹ́ ogun Ọlọrun, ani ẹgbẹrun ati ẹgbẹgbẹrun: Oluwa mbẹ larin wọn, ni Sinai ni ibi mimọ́ nì. Iwọ ti gòke si ibi giga, iwọ ti di igbekun ni igbekun lọ: iwọ ti gbà ẹ̀bun fun enia.”

A sọ fun wa pe ni igba laelae, bi olori ogun kan ba ni iṣẹgun nla kan, oun yoo ṣaaju awọn igbekun rẹ̀ la igboro, yoo si maa fọ́n ẹ̀bun jade lati inu ọpọlọpọ ẹ̀bun ti o ti gbà.

Debora kọrin bayii ninu orin iṣẹgun rẹ̀, “Ji, ji Debora; Ji, ji, kọ orin: dide, Baraki, ki o si ma kó awọn igbekun rẹ ni igbekun” (Awọn Onidajọ 5:12).

A mọ̀ pe nigba ti Jesu jinde kuro ninu oku, o jade wá pẹlu iṣẹgun lori ẹ̀ṣẹ, ikú ati ọrun-apaadi. Nigba ti O goke lọ si Ọrun, O rán Ẹmi Mimọ́ sọkalẹ sinu ayé yii O si fi ẹ̀bun fun awọn eniyan. Wo iru alaye daradara yii!

Boya aṣepari ohun gbogbo yoo jẹ́ igba ti Jesu ba pada wa si ayé lati ṣakoso ati lati ṣe aṣiwaju awọn eniyan mimọ́ Rẹ̀ la igboro ilu nla Jerusalẹmu ti yoo si yan ipo fun wọn lati ba A jọba.

Awọn ẹsẹ Iwe Mimọ́ wọnyii n la wa ni òye nipa ohun ti Jesu ṣe laaarin ikú ati ajinde Rẹ̀. Ohun ti O waasu tabi ti o kede fun awọn ti o wà ni ipo-oku ni awa ko mọ. Bibeli ko sọ fun wa.

Awa mọ lati inu ọpọlọpọ ẹsẹ Iwe Mimọ pe ko tun si anfaani mọ lẹyin ti a ti kú tán lati le ri iye ainipẹkun, “Niwọn bi a si ti fi lelẹ fun gbogbo enia lati kú lẹ̃kanṣoṣo, ṣugbọn lẹhin eyi idajọ” (Heberu 9:27). Kò si ibi-iwẹnu nibi ti a le lọ ki a si wà nibẹ titi alufaa yoo fi fi adura yọ wá jade.

A ni akọsilẹ ohun ti Jesu sọ nipa ọkunrin ọlọrọ ni ati Lasaru. Ọkunrin ọlọrọ nì bẹ Abrahamu pe ki o rán Lasaru pada sinu ayé yii lati kilọ fun awọn arakunrin oun marun-un ki wọn má ba wá si ibi iṣẹ oró naa. Abrahamu wi pe, “Bi nwọn kò ba gbọ́ ti Mose ati ti awọn woli, a ki yio yi wọn li ọkan pada bi ẹnikan tilẹ ti inu okú dide” (Luku 16:31).

Ẹlẹṣẹ ti ko ba ronupiwada awọn ẹ̀ṣẹ rẹ̀ ki o si ri idariji fun wọn gba nigba ti o ṣi wà ninu ayé yii, kò ni anfaani lati bọ́ lọwọ idalẹbi ọrun-apaadi.

Ọlọrun rán Jesu wá si ayé yii o si fi àye silẹ fun Un lati kú lori agbelebu ki awa ki o ma ba ṣegbe ṣugbọn ki a le ni iye ainipẹkun. O fun wa laayè nihin ni gbogbo ọjọ ayé wa lati yan ibi ti a o ti lo ayeraye. Ṣugbọn niwọn igba ti a ba ti rekọja, abá ati là kò si mọ́.

**Idanwò bi Iná**

Nigba miiran awọn Onigbagbọ́ a maa la idanwò bi iná kọja: iyiiriwo nipa inunibini, iyiiriwo nipa ibanujẹ ọkàn, iyiiriwo nipa aisàn ati ipọnju. A sọ fun wa pe ki a yọ̀ niwọn igba ti a jẹ alabapin ninu iya Kristi. Ogo Jesu yoo pọ̀ nitori ijiya ti o le eyi ti O là kọja lati mu eto irapada ṣẹ. Bi a ba jiya fun Un nihin, ayọ̀ wa lọhun yoo pọ ju bẹẹ lọ. Bi a bá le di otitọ yii mú, yoo ràn wá lọwọ lati mú ki

ẹrù idanwò wa bi iná ki o fuyẹ. Bi a ba jiya gẹgẹ bi Onigbagbọ́, a kò gbọdọ tiju; ṣugbọn bi a ba jiya fun iwa aitọ́ wa, eyi yoo mú ẹgan wa sori wa ati sori Ihinrere Jesu Kristi.

Idajọ bẹrẹ lati inu ile Ọlọrun lọ. A ko le ṣe ohun ti ko tọ ki a si ro pe a o lọ lasan. A o ká ju eyi ti a gbin lọ. Ọpọlọpọ igba ni Oluwa maa n nà wá lati mu wa pada bọ̀ si oju ọna. Wo o bi o ti sàn tó lati mọ ẹgba ibawi nihin yii ki a si jere nipa rẹ̀ ju lati jiya titi ayeraye! “Biobaṣepe agbara káka li a fi gba olododo là, nibo ni alaiwà-bi-Ọlọrun on ẹlẹṣẹ yio gbé yọju si?” (1 Peteru 4:18).

**Iṣẹ Oluṣọ-Agutan**

“Ẹ mã tọju agbo Ọlọrun”. Peteru ko jẹ gbagbe ẹkọ ti o kọ́ gẹrẹ lẹyin ikú ati ajinde Jesu. Fun ju bi odididi ọdun mẹta ni o ti n tẹle Oluwa lẹyin. A ti pe e jade lati inu fifi awọ̀n pẹja lati di apẹja eniyan. Ṣugbọn nisisiyii ti o ti rẹwẹsi, ti ko ni ibalẹ ọkàn, ti ara rẹ̀ ko si lelẹ, o wi fun diẹ ninu awọn ọmọ-ẹyin pe, “Emi nlọ ipẹja.” Wọn wi fun un pe, “Awa pẹlu mba ọ lọ.” Ko si igba kan ti a ba yapa ti a ki yoo ko eeràn ran awọn ẹlomiran.

Jesu ko fi i silẹ ni ipò irẹwẹsi yii ṣugbọn O ṣe iṣẹ iyanu lati fi hàn fun awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀ pe Jesu kan naa ni Oun I ṣe bi ti akoko ti Oun n ba wọn rin ni eti okun Galili. Lẹyin ti o fi ounjẹ bọ́ wọn tán O sọrọ ti ó wọ Peteru lọkàn. “Simoni, ọmọ Jona, iwọ fẹ mi bi?” Jesu beere ibeere yii nigba mẹta. A gbagbọ pe bi ibeere yii ti n jade ni o tubọ n jinlẹ si i ninu ọkàn Peteru pe oun ki yoo yà kuro loju ọna mọ́. Nigba ti Jesu sọ fun un pe ki o maa bọ awọn “agutan” Oun, Peteru kọ́ ẹkọ ti ko jẹ gbagbe lae.

Nisisiyii Peteru n gba awọn oluṣọ-agutan iyoku niyanju lati maa tọju agbo Ọlọrun ki wọn ṣe e tifẹtifẹ, ki i ṣe fun owo oṣu tabi fun ere owo ti wọn o gbà; ki i si i ṣe gẹgẹ bi oluwa lori ijọ Ọlọrun. Ki wọn maa fojusọna fun ere wọn nigba ti Olori Oluṣọ-agutan yoo fi ara hàn.

Ẹ mã wà li airekọja, ẹ mã ṣọra; nitori Èṣu, ọtá nyin, bi kiniun ti nke ramuramu, o nrin kãkiri, o nwá ẹniti yio pajẹ kiri: ẹniti ki ẹnyin ki o kọ oju ija si pẹlu iduroṣinṣin ninu igbagbọ́, . . . . . . Ọlọrun ore-ọfẹ gbogbo, . . . . yio si ṣe nyin li aṣepé, yio fi ẹsẹ nyin mulẹ, yio fun nyin li agbara, yio fi idi nyin kalẹ (1 Peteru 5:8-10).

## AWỌN IBEERE

1 Bawo ni aya ṣe ni lati huwa si ọkọ alaigbagbọ́?

2 Bawo ni ọkọ ṣe ni lati huwa si aya?

3 Iru ọṣọ wo ni o sàn ju wiwọ aṣọ olowo iyebiye lọ?

4 Ki ni ere wa nigba ti a ba jiya fun Kristi?

5 Ileri wo ni yoo ràn wá lọwọ lati la idanwò wa bi iná kọja?

6 Awọn wo ni o ni lati maa tọju agbo Ọlọrun?

7 Ẹkọ wo ni Peteru kọ́ nipa titọju awọn agutan Kristi?

8 Ta ni ẹni ti o n gbiyanju lati pa awọn agutan jẹ?

9 Ọrọ iyanju wo ni Peteru fun wa lati ràn wá lọwọ lati di amure idoju-ija kọ ọtá?

10 Darukọ ohun mẹta ti Jesu ṣẹgun nipa ikú ati ajinde Rẹ̀?